E ṣe ìgbìyànjú igbogunti awon olusẹbọ pẹlu Ọlọhun pẹlu owo yin ati èmi yín àti ahán yin

Láti ọdọ Anas - ki Ọlọhun yọnu si i - dájúdájú Anọbi (kí ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a) sọ pé: "E ṣe ìgbìyànjú igbogunti awon olusẹbọ pẹlu Ọlọhun pẹlu owo yin ati èmi yín àti ahán yin".

[O ni alaafia] [رواه أبو داود والنسائي وأحمد]

Anọbi (kí ikẹ Ọlọhun ati ọlá Rẹ máa bà) pa wà lasẹ lati gbógun ti alaigbagbọ, ki a sì ná ìgbìyànjú láti dájú kọ won pẹlu gbogbo ọnà tí a ni ìkápá le lórí nítorí kì gbólóhùn ati ọrọ Ọlọhun le wa loke, nínú ìgbìyànjú náà ni: Alakọkọ: nina owó àti dukia lati fi gbógun ti won, bí rírà nkan ijagun, ati ìnáwó lórí awon jagunjagun ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ẹlẹkeji: ki a jàdé pẹlu emi ati ará lati lọ pàdé won ati lati da won pàdà. Ẹlèkẹta: pẹlu pípé won síbi ẹsin Islam yi pẹlú ahán, ati ifi idi ọrọ ati ẹri rinlẹ fún won ati ijagbe mọ won ati ìfun won lèsi.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/64597